# OLOPA MU ADELABU FUN ESUN OWO IBOLE





*AWOGBA Omode fun Girl, Eri, Hihu-chin, Orere, Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*



# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



*TO CLEAR*

*Gents Suede Court Shoe, Brown, Black & Grey. Before 50/- Now 42/6d*

Obtainable at :-

A. B. AKINYEMI

*10A Moloney Bridge St*



VOL. VIII No. 459. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 17, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)


## Olopa Mu Adelabu Fun Esun Owo Ibole

Ọgbẹni Adegoke Adelabu ti o ti jẹ Minister a t i Alaga Igbimọ ibilẹ nilu Ibadan ri, ni a gbọ wipe ọlọpa ramu ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọsẹ yi fun ẹsun owo ibọlẹ gbigba lori a b ọ iwadi t i Ọgbẹni Nicholson ṣ e nigbati nwọn ṣe iwadi i w a wuruwuru n i n u Igbimọ ibilẹ Ibadan.

KILO FA SABABI ?

Nigbati Ọgbẹni E. W J. Nicholson nṣe iwadi i w a ẹgbin, iwa aiṣododo to gbojikan ninu Igbimọ ibilẹ ilu Ibadan, ni Ọgbẹni Samuel Ogunṣọla ti Abule Ọgunrin lẹ'ba Ibadan tu aṣiri wipe on lọ sọdọ Ọgbẹni Adelabu wipe ki o ṣe iranlọwọ fun on ki ọmọ on ti orukọ rẹ njẹ James Adigun le ri aye w ọ iṣẹ Aṣọgbo. O ni Adelabu sọ wipe, yio bẹsi, ṣugbọn owe ni yio jẹ.

Lẹhinna ni James Adigun kọwe iwa'ṣẹ (application) ti Ogunṣọla mu lọ fun Adelabu ni Gbọngan Mapo (Mapo Hall) nigbati Ogunṣọla jade ti o nlọ, Ali tẹle o si sọ fun wipe Alaga nfẹ pọnwun m ẹ w a. Ogunṣọla s ọ wipe on ran Ladejọ l ọ b a ọmọ on ni ile iṣẹ Alabojuto

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


VOMICURE




*A Very Reliable Remedy for Vomiting During Pregnancy. Loss Of Apetite, Pains Below the Abdomen And All Other Ailments That Make Pregnancy Uncomfortable. No Prescription Needed. Just Buy A Bottle And Enjoy Good Health.*

*Obtainable from:-*

EJIWUNMI MED. STORE LAGOS.

and Many other Medicine Stores



## THE NATIONAL BANK

### Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onişowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—

37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## ALAKOSO IJOBA



SIR ANTHONY EDEN.

Aworan Oloye nla Anthony Eden, t i işe Alakoso Ijọba ilu Oyinbo Gẹsi, o t i nṣe akọwe awọn i l u okere lati ọdun 1935 to f i di ọdun 1938 n i gbogbo asiko rogbodiyan ogun ajakaiye keji n i n u ọdun 1940 to fi di 1945, ati ninu ọdun 1951 t i t i t o f i gba ipo Alakoso Ijọba (Prime Minister).

Lati inu ọdun 1955, l'o ti di Alakoso I j ọ b a nigbati Ọlọla Sir Winston Churchill, K G, fi aye ipo na si'ẹ o si ti wa ninu ajọ Igbimọ nla tilu Oyinbo Gẹsi fun ilu Warwick ati Leamington nigba to ti di ọmọ ọdun mẹrindinlọgbọn ni ọjọ ori rẹ, aye na l'owa titi to fi gba ipo Alakoso Ijọba.

Nipa iwa ọgbọn, ero ijinlẹ l'ori ohun gbogbo ati suru rẹ to fi ma a nri si awọn ohun to ba nda awọn ilu miran l'amu, jẹki orukọ rẹ tan kalẹ gbogbo agbaiye ti awọn Ọjọgbọn agbaiye ti mbu ọla fun u.

## Ile Ise Owo-Ori Jona.

BENIN: Ni owurọ ọjọ Tuesday ọsẹ yi ni a gbọ w i p e Ile iṣẹ Owo-Ori ti ilu Ibini j'ona rau-rau. Gbogbo awọn iwe pataki ni o j'ona patapata.

A gbọ wipe ni ọsẹ tokọja ni Olofintoto owo t i Igbimọ ibilẹ (Council's Auditor) lọ si ile iṣẹ na lojiji, o si bẹrẹ si ṣe ofintoto awọn Iwe owo, a ko si gbọ wipe owo s'ọnu tabi pe ole jẹ. Ṣugbọn nigbati gbogbo iwe pataki-pataki ti j'ona yi, iṣẹ ti alayẹwo (Auditor) duro.

Awọn ọlọpa ti bẹrẹ s i ṣe iwadi ohun to fa sababi i n a n a wa nisisiyi.

## ILE OBA ILU Oyinbo



Aworan ile ẹwa ti ẹ nwo yi ni ibugbe awọn ọba ilu Oyinbo Gẹsi ti a npe ni Afin Buckingham (Buckingham Palace), Ibẹ ni ibugbe ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi to bẹ ilẹ wa nihin wo pẹlu ọkọ rẹ l'oṣu tokọja.

Awọn iyara to wa ninu ile n a le l'ẹgbẹta ọkan pataki ni ile na jẹ ninu olu ilu Oyinbo Gẹsi. Ọmọ'ba oloye Duke of Buckingham l'okọ Ile nla na ninu ọdun 1703, ki ọba George Kẹta to ra ile na lẹhinna ni NASH tun ile n a ṣe fun ọba George Kẹrin.

Ọba obinrin oninurere, Victoria ko sinu ile nla yi ni ọdun 1837 ninu ọdun 1913 ni wọn fi okuta Portland ti oloye Sir Aston Webb, P. R. A. ṣe ni alarabara tun iwaju ile na ṣe. Bi o ba tiri Asia to nfẹ lẹlẹ lori ile yi, ki o mọ wipe Alaiyeluwa Ọba mbẹ nile.

---

## Itan Ku Ku Ku Nipa Awon Alagbara Ile Yoruba

Lati Ọwọ Eṣọ Ikoyi

### ỌRUNMILA

Ojẹ ọkunrin alagbara kan nilẹ Yoruba, t i awọn Babalawo sọ fun wa wipe, on lo mu odu kan wa lati ọrun ti o fi wa tun aiye Ifẹ ṣe nigbati awo Ifẹ fẹ bajẹ Orukọ baba rẹ ni Ifa Ọpẹriti, Iya rẹ a si majẹ Poroye Ogidi. Awọn mejeji nwọn yi lobi Orumila si Ile Ifẹ Ọyẹlagbo, ladugbo kan ti a npe ni Oke Igẹti.

Lasiko ti a bi Ọrumila yi si ile Ifẹ Ọyẹlagbo, ọba ti o mbẹ lori oye ni Ifẹ lasiko na ni Ọba Ajalọrun Ataiyeṣe. Ki o to to akoko ti Ajalọrun gun ori oye ọba. Ọlọja-lọja ni a npe awọn ọba nigbani,

Lọjọ ti nwọn bi Ọrumila n i awọn ọdẹ Ọlọfin mẹta pa ẹran abami mẹta lọjọ na. Ẹrin, Ẹfọn ati Agbọnrin Orukọ awọn ọdẹ na n i Orisi-tasi Orisitasi ati Atamata e, Erin ti Orisi-tasi pa, nigbati a nkun u nwọn ba ọmọ titun to diwọ - disẹ ninu rẹ. Nigbati nwọn kun Ẹfọn ti Orisitasi pa, nwọn ba igba funfun adeiṣi ninu rẹ. Nigbati nwọn nkun agbọnrin t i atamatase pa nwọn ba Ikin mẹrindilogun ti o funfun pẹn ninu rẹ.

... Odumare fi fun Ọrumila lati ma fi wadi ... ti o mbẹ lọrun ati laiye awọn arọkan sọ wipe lẹhin ti baba Ọrumila ku tan ni Ọrumila ... ki ... pada si Ifa, nitoriki orukọ baba rẹ Ifa, Ọpẹr ti ma ba parẹ. Iṣẹ iyanu pupọ ni a gbọ wipe Ọrumila ṣe laiye,

Odu Ifa kan sọ fun wa pe nigbati Ọrumila ti lọ gba ọpa Ọtọt tọ wa si aiye, a ma fi la oju afọju, an u ... orin, arọ ndide ati bẹ, bẹ, Ipasẹ Ọrumila ni nwọn ... wo ntọ. Nigba aiye Ọrumila, a ma de fila gobi, a fi ... ji bo mọlẹ, yio wọ ẹwu agbada, yio so iẹkẹ mọ ọwọ, yio wọ ṣokoto Labu yio mu ọpa Ọtọtọtọ rẹ dani yio si gbe apo Ifa rẹ kọ ko nwọ bata

Bayi ni Ọrumila nki Odumare bi o baji lowurọ, Moji, mo ki Akọda, aṣẹda. asunrunnẹnẹ, Awo ji ki lawo ajiki awo ajiki lawo ajiki, ati dide li a mọ awo ajalẹgbun, Ina kukuku li ahere, enia kukuku li aba, Oluwa mi ọgbọjọ, ti awo yọ ọgbọjọ, ma-ma jẹki tirẹ yọ o;

Ki Orumila to pe awọn gbolohun oke yi, yio kọkọ wẹ ọwọ finni yio wẹ ẹsẹ finni, yio si wẹ gbogbo ara finni-finni nitori ire ara eni Odumare ko fẹran ẹgbin lẹhin eyi Ọrumila yi bẹrẹ si wure fun ara rẹ bayi wipe, Iworiwola !! Iworiwo iẹki ọna ire la kan mi loni. Iworiwola! moji, mo ki Atọla, Asula. Asurunini, Afunyẹnkẹn, Akẹyẹnkẹn, Ọwẹnwẹn Akẹ-bi-ala Mo wari fun ọ loni, mo wabọ fun ọ loni, iẹki ngbo ki ntọ, Iworiwola! jẹki ọna ire la fun mi o, Iworiwola.

Ọrunmila jẹ ẹniti o ni suru, a si ma wadi ohun-gbogbo daju ki o to dawọ le ohun na. nipa eyiyi lo fi bori gbogbo idanwo aiye ti o de si Ohunkohun ti o ba kan ni etutu ko nfi jafara. kiakia ni yio ṣe.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

---


## LAGOS RACE CLUB

The Race for the Christmas Sweepstake, unavoidably delayed due to the Royal visit to Nigeria, will now be run on SATURDAY THE 24th MARCH. The draw will take place at the Island Club on TURSDAY THE 22nd MARCH At 6.30 P.M. Please note that all tickets must be returned to Lagos Race Club by MARCH 20th. Late returns will not be accepted.


## Western Region Production Development Board.

# Vacancy For Senior Stores Assistant.

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Senior Stores Assistant in the Stores Section of the Board. Salary will be in the scale £354 x 18 - £426 per annum, entry point depending on qualifications and experience.

### QUALIFICATIONS

Applicants must be fully conversant with Store Rules and procedure. Preference will be given to candidates who possess a thorough knowledge of vehicle-spare parts in respect of at least one of the following: Bedford, Land Rovers, Ferguson Tractors and Trailers.

### DUTIES

The selected candidate will be required to undertake, in addition to general store keeping, duties connected with the safe custody of all Board's vehicle spare parts. He will be responsible for the selection of vehicle spare parts and engineering equipment and will be required to enter into a Bond with the Board.

Applications accompanied by copies of certificates and two recent testimonials together with names of Bondsmen should be addressed to :-

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Secretariat, Ibadan.

to reach him not later than 15th April, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

# Irohin Ilu Oyinbo

ẸGBẸ ỌMỌ OGUN ILẸ NIGERIA

Lati ọwọ Ọgagun Gbogbogbo C. R. A. Synnerton.

Ninu awọn ẹgbẹ ogun ti o wa ni apa Iwọ-orun Afrika ẹgbẹ ti o wa ni Nigeria ni o dagba ju, ẹniti o si jẹ ọgagun agba pataki fun ẹgbẹ yi ni ọlọla nla julọ, Ọba Elizabeth keji ti ilẹ Gẹsi

Fun akoko pipẹ ni awọn oyinbo fi nfi ara wọn tọrẹ fun awọn ẹgbẹ ologun yi ni ninu eto akoso Titi o si fi di igbati ogun ajakaiye pari ni awọn oyinbo wọnyi wa ni ipo ọgagun, sugbọn nisisiyi wọn ndinku diẹdiẹ a si nri awọn enia dudu ti wọn wa ni iru ipo ọga bayi.

ETO ẸKỌ AWỌN OLOGUN

Gbogbo awọn enia dudu ti wọn wa nipo ọga ninu ẹgbẹ ogun ni wọn ngba ẹkọ yala ni ile ẹkọ ologun ti sandhurst gẹgẹbi ẹniti yio ma lọ dede ninu aṣẹ ti wọn fun, tabi ni gbọgan Eaton bi ọgagun ti o wa fun igba diẹ. Ẹniti o ba si jẹ, olu wadi ti o f'arabalẹ dada, ti o si ti bẹ ẹgbẹ ọmọ ogun Nigeria wo, yio ya lẹnu pupọ lati rii bi awọn ọgagun kekeke ati awọn ọgagun pataki wọnyi ti nṣiṣẹ bi alakikanju ti enia le gbẹkẹle. Lati igbati awọn ẹgbẹ onişowo ti a npe ni Royal Niger Company ti nṣowo kakiri apa Iwọ-orun Africa ni awọn ẹgbẹ ọmọ ogun Nigeria ti wa. Ogun akọkọ ti wọn si kọ ja ni ti Ashantee bii ọdun mẹta-lelọgọrin sẹhin. Awọn ọmọ ogun wọnyi tun wolo fun Ọlọla Wolseley ninu irin ajo ti o ṣe ni Ashanti bi ọdun meje lẹhin na. Wọn tun foju gbina lati ṣẹgun awọn ọmọ ogun ti Germany ninu ogun ajakaiye kini, lẹhin eyi ni apa Iwọ-orun ilẹ Africa awọn ọmọ ipin ogun keji ti ẹgbẹ Nigeria ti Oba Obinrin ilẹ Nigeria yio ṣe lọsọ ni ọgbọnjọ oṣu, ṣe gudugudu meje ni ilu ti a npe ni Nyangao.

Orişirişi işẹ ni o wa ninu ẹgbẹ ọmọ ogun Nigeria. Gbogbo iṣẹ ti awọn ologun nṣe patapata ni o wa nibẹ. Ọna ti ilẹ Gẹsi ni wọn ngba lati fi kọ awọn ọmọ ogun awọn miran ti wọn nkọ fun ipo ọgagun wa kakiri ilẹ Gẹsi nisisiyi. Gbogbo awọn ti wọn nkẹkọ wọnyi ni wọn nṣe dada, ọpọlọpọ igba ni irohin si ma nkan wipe wọn fẹran wọn.

AWỌN ỌMỌ OGUN WỌNYI JA NI BURMA

Ninu ogun ajakaiye keji, awọn ọmọ ogun Nigeria ati ti Rhodesia ni wọn darapọ lati fun awọn ọmọ ogun Europe ni agbara. Ninu ogun ti wọn ja ni apa ila-orun Africa lati odo Juba titi de ẹnu odi ilu Addis-Ababa, orişirişi awọn ọmọ ogun Nigeria ni wọn jumọ ja bi alakikanju ti wọn si gbogun ti Ọta lọna lọna.

Ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ ogun wọnyi ni wọn lọ fi oju gbina ni Burma ti wọn si di ẹya "Chindits", A ọn yio ku si wa di ara awọn ipin ọmọ ogun apa iwọ-orun Afrika kọkanlelọgọrun ati ikejilelọgọrin

Ninu ogun ti wọn ja ni Burma, awọn ọta fi ẹsẹ rinlẹ daindain pupọ, akoko wa le pupọ fun wọn. Bi ija ti gbona janjan to yi awọn ọmọ ogun Nigeria ati awọn miran tẹ siwaju.


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN



## Kere o!

A ti ni origirişi ogun Germany to şẹşẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos



*to protect your cocoa from black pod disease and capsid*





**FOUR OAKS**
spraying equipment
*is the best!*





- *effective*
- *easy to operate*
- *safe*
- *increases yield*

FOUR OAK sprayers are available through your local Cooperative Supply Association Shop or Depot or through any Co-operative Produce Marketing Society or Union.

COOP
WESTERN NIGERIA

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS — "ELETI – ỌFẸ LAGOS" Phone 23370

VOL. VIII. NO. 459. LAGOS, SATURDAY MAR. 17, 1956.


## Alo A Dara, Abo A Sunwon! O

N ọ'ọ Monday ọsẹ yi ni Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolowọ ti iṣe Alakoso Ijọba Iwọ-orun wọ Ọkọ Ofurufu ni Ikẹja pẹlu awọn isọngbe rẹ ti nwọn mu ọna irin-ajo wọn pọn lọ si ilu Oyinbo Gẹsi, Amẹrika, Kanada, Romu, Jamani, to fi de Jepani, lati lọ kede fun Ẹlọwọ nipa ifọwọsopọ lori idide ipinlẹ Ijọba Iwọ-Orun.

Gẹgẹbi gbolohun ti Oloye Awolọwọ sọ ki o to wọ'kọ ni Ikẹja wipe "Awa ti mura pẹlu eto pipe, a si ni ifọkanbalẹ fun rere." mu ki inu wa pẹlu aileka-tan ọpọ enia dun gidigidi si idide ti awọn Olotu Ijọba wa dide si iṣẹ nigbati asiko na to, laisi wipe ki wọn ti fi kẹkẹ ṣiwaju Ẹṣin, ki irin ajo wa di arin tun rin. Ṣugbọn gbogbo enia ni o mọ wipe Olotu ati akonijẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) ko jẹ fi wadu-wadu j'ada l'ori ikọ.

### GELE 'O DUN BI K'AMỌ'WE

K'ari owo ra ẹlẹya, ko dabi ki o yẹni ni owe awọn Yoruba, emi ni ọga, emi ni olori ko dabi ẹniti Olodunmare yan ti o fun ni ọgbọn ati ọna eto lati gbe ilu dide gẹgẹbi orilẹ-ede ti Ọlọrun fi Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ta wa l'ọrẹ ni ipinlẹ Iwọ-Orun, ti ko si afiwe rẹ ni Nigeria wa yi.

Adura atọkanwa tiwa ni wipe ki alọ wọn ki o dara, ki abọ ki o sunwọn, ki wọn ko ere oko bọ wa'le Amin, Aṣẹ, bẹni ki ori!

No. 73/S.2/VOL. VI/69

### Ministry Of Education, Western Region

TEACHERS' CERTIFICATE EXAMINATION, GRADE III. 1956.

The examination will be held on 13th, 14th and 15th of November, 1956.

Papers will be set in (1) English, (2) Arithmetic, (3) History and Georgraphy, (4) Nature Study and Hygiene, (5) School Method, (6) School Organisation.

Referred candidates must apply NOT later than 31st May, 1956 to the Principal of the College in which they were trained stating the subjects in which they were referred and the CENTRE at which they wish to re-take the papers.

F. K. Butler
Director of Education,
Western Region.






## WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.

## Clerk Of Works.

The Board invites applications for the post of Clerk of Works who will be responsible for the inspection, maintenance and repair of buildings.

Candidates should have served a full apprenticeship in one of the Building trade and served as General Foreman or Contractor's Agent on large contracts, or have had previous experience as a Clerk of Works.

Salary to be paid will depend upon qualifications and experience of the successful candidate and will be in the range of £660; £700 x 42 - £868; £902 x 42 - £1, 070 (plus expatriation allowance where applicable). Point of entry will depend on the candidate's qualification and experience.

Applications, in the applicant's own handwriting, giving full details of qualifications and experience, should be fowarded to :-

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board, Ibadan,
to reach him not later than the 26th of March, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.




**Designers like**

**Capstan**

**they're blended better**

NO. 73/s.2/VOL.VI/69

## Ministry Of Education Western Region

TEACHERS' CERTIFICATE EXAMINATION, GRADE II 1956.

1. The written examination for the Teachers' Certificate Grade II will begin on 29th November, 1956.
2. Full details are shortly to be published in the Gazette of the conditions for the award of the Certificate and the syllabuses in each subject.
3. Internal candidates must apply through the Principal of the College.
4. Internal referred Candidates (candidates who have completed a full course of Teacher Training for the Grade II or Higher Elementary Certificates) MUST apply to the Principal of the College in which they were trained stating the year and subjects in which they were referred and the CENTRE at which they wish to repeat the papers.
5. External candidates (candidates who have not completed a full course of Teacher Training for the Grade II Certificate) and external referred candidates should obtain application forms from the Provincial Education Office which should be completed and returned to the Senior Education Officer in charge of the Province.
6. A non-returnable fee of £3. 3s must be paid by all external candidates. Payment should be made to the nearest Government Treasury and a receipt obtained.
7. Entries close on 31st May, 1956. Late applications will not be accepted.
8. The Director of Education will NOT enter into any correspondence with individual candidates. Candidates are warned that letters or applications sent direct to Headquarters may be ignored.

F. K. BUTLER
Director of Education, Western Region.

## Western Region Production Development Board.

### Foreman Of Works Grade II.

Applications are invited for the above post. Candidates should have a wide experience in building and Civil Engineering Contract and should have served apprenticeship in one of the Building trades preferably that of Carpentry and Joinery.

Salary to be paid will be in the range of £354 x 18 - £426; £448 x 24 - £520: point of entry depending on experience.

Applications, in the applicant's own handwriting, giving full details of qualifications and experience, should be forwarded to :-

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board,
IBADAN,

to reach him not later than 26th March, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

### IMORAN FUN EYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ e wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa Lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## AKIYESI PATAKI

**Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,**

LỌ SI:-

**18, Race Course Road,**
OKE—PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—OFE nigba gbogbo.

## AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN FI YE WA WIPE

BI A BA NFI EGBOGI







COLGATE DENTAL CREAM FO EHIN

KO NI JEKI EHIN ENI BAJE, O DARA PUPO



Iṣẹ ti Egbogi yi nṣe ni wipe, eyiti o nho bi ọṣẹ yẹn, yio wọ gbogbo pala-pala ehin, yio si yọ gbogbo ajẹsi kuro, ko ni jẹki enu run, ko si ni jẹ ki ehin bajẹ.




O njeki ehin funfun, enu ko si ni run mo.

## Western Region Production Development Board.

### DISTRICT INSPECTOR OF WORKS (WATER).

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as District Inspector of Works (Water).

Candidates should be conversant with the laying and Servicing of Everite and Iron Mains, installation and servicing of both Centrifugal and Piston Type Pumps and Diesel Engines and be able to undertake complete overhaul of such equipment. At least ten years previous experience is necessary.

Salary will be in the range of £660; £700 x 42 - £863; £902 x 42 - £1,070 (plus expatriation pay where applicable), point of entry depending on qualification and experience.

Applications, in the applicants own handwriting, giving full details of qualifications and experience, should be forwarded to reach

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board, Ibadan

not later than the 24th of March, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.


## FUN FIFO EHIN FUNFUN DARA-DARA ATI IGBADUN ENU




## Ma Lo Egbogi COLGATE Chlorophyll Ti A Fi Nfo Ehin.

Ma fi egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin fọ ehin rẹ nigba gbogbo. Işẹ iyanu rẹ ko mọ lori ki ehin rẹ ma bajẹ, ki o mọ, ki o si fun-fun nikan, o tun, npa kokoro ehin, ko si ni jẹki akokoro yọ'nu.

Ri daju pe o nlo egbogi Colgate Chlorophyll ti, a fi nfọ ehin nigba gbogbo. Egbogi alawọ ofefe ti nbo bi ọṣẹ.




Bere egbogi ti Colgate alawọ ofefe ti a fi nfọ ehin


WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## Press Notice

### Rubber Processing Factory,

### IKPOBA, BENIN CITY.

**It is notified for general information that a large number of applications for employment have already been received by the manager of the above factory and that further applications wil not be required. In the future, such letters will not be acknowledged.**

**M. D. T. FARR**
**Factory Manager.**

No. 73/S.2/VOL. VI/72

## QUEEN'S SCHOOL WESTERN REGION EDE

### ENTRANCE EXAMINATION 1956

The annual examination for admission to Queen's School, Western Region, Ede, in January 1957, will be held on Saturday, 26th May, 1956. There will be examination centres at Lagos, Ibadan, Ede, Benin-City, Akure, Ado-Ekiti, Abeokuta, Ijebu-Ode and Owo.

2. The examination is for the admission of boarders to Secondary Form I Only. Papers will be set in English and Arithmetic and will be based on the syllabus for Primary Standard V. No entrance fee is payable.

3. The fees, including Board and Tuition are £30 a year. Pupils are also required to pay for uniform which costs approximately £5, pens, pencils, a ruler, bed linen and a Blanket, toilet necessities and transport to and from school. The school provides exercise and text books, a matress, pillow and mosquito net.

4. The following will be eligible to sit the examination:-
   - (a) Girls eligible to sit the Western Region Primary School Leaving Certificate Examination in 1956.
   - (b) Girls who passed in the Primary School Leaving Certificate Examination held in 1955 and who have not entered a Secondary School at the date of the examination.
   - (c) Girls of Western Parentage -
     - (i) who are attending schools in other Regions and are not below Standard V or
     - (ii) who have a Leaving Certificate gained in 1955.

5. Girls at present in Secondary Grammar and Secondary modern schools will not be eligible to sit Queen's School Entrance Examination.

6. Names of candidates should be submitted by their Headmaster on the forms which may be obtained from.

The Principal,
(Application Forms)
Queen's School,
Ede,

and must be returned before 9th April. Girls in the category in paragraph 4 (b) should apply through the Headmaster of the school they were attending in October, 1955. No correspondence from individual candidates will be considered.

7. A number of candidates will be called for further examination and interview on the result of which the final selection of the successful candidates will be based. Only successful candidates will be informed of the result and a list of the successful candidates will be Published in the Western Region Gazette.

8. No reply will be sent to letters on the subject of the acceptance or rejection of candidates for this examination.

L. DICKINSON
Ag. Vice-Principal

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko şişẹ to o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amodi bayi lati se şegbogi DE WITTS, y i o si fun enia ni igbadun ara

Kakiri niye ni egbogi yi ti nse iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni şọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba şişẹ tara, şugbọn bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio de si oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti şişẹ. Danwo lọ ra ni şobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles



## Enjoy Your Own —Songs—

Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is



**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . . THROUGHOUT . . . . . . . . . . . NIGERIA . . .**



**Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki O Si Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Aladun Yi**


## Owo Olopa Te Ole Nilu Ibadan

IBADAN. Larin ilu Ibadan ni a gbọ wipe awọn Ọlọpa lọ şe ofintoto ile ti awọn ole gbe nsira si, ni adugbo kan ti a npe ni Agbẹdẹ-Adodo

Nigbati awọn Ọlọpa bẹrẹ si tu awọn ile adugbo yi wo, a gbọ wipe enia meji ni ọwọ tẹ, Muili Ajani, o t o ọmọ ọdun mẹtale-lọgbọn, ati Ganiyu Akanbi, ọmọ ọdun mẹtalelogun ara ile Ifẹ, awọn Ọlọpa si ti mu w ọ n l'ọ s i Şobu Ọlọpa l'Agodi.

A gbọ wipe ọpọlọpọ irin lşẹ ti nwọn fi-nfọ'le ni wọn ba ninu ile Muili, ninu ile ẹnikeji, idi (bundle) Igbo kan (Indian Hemp) ni wọn ri nibẹ. A gbọ pe ọrọ wọn yio de iwaju adajọ.

## Ibere Oro

OLOTU,

Ẹjọwọ, ẹ gba mi laye lati bere ọrọ yi lọwọ awọn ọkawe rẹ, ki ẹniti oba ni imọ fi ye mi.

Awọn ọrẹ mẹta kan wa orukọ ekini a majẹ Kigbọ, ekeji Olojukokoro, ẹkẹta Idarudapọ Awọn mẹtẹta ni o nfẹ iyawo kan, tani o tọ ki wọn fun ni iyawo ninu awọn mẹtẹta ?

Emi ni ọmọyin totọ
G. A. Ọlanrewaju.

## Ole Ko'le Oloye Awolowo

IBADAN: Ni o r u ọjọ Monday n i a gbọ wipe awọn ole lọ ko ile Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o kuro nile ni ọjọ ọsẹ (Sunday) wa si Eko lati le wọ ọkọ ofurufu lọ si irin ajo rẹ pẹlu awọn isọngbe rẹ lori ipinlẹ Ijọba Iwọ-orun

A gbọ wipe awọn ole na ko ẹru bi o n i rinwo pọnwun (£400) a w ọ n ohun ọşọ Golu ti Oloye H. I. D Awolọwọ ti işe iyawo oloye Awolọwọ pẹlu ẹru ti Alakoso Ijọba papa ni awọn ole na ko lọ.

Awọn Ọlọpa Ibadan ti bẹrẹ si şe iwadi nipa rẹ.

## Irohin Ile Ejo

Simeon Ejes ni ọmọ ọdun mẹtalelogun ti o nşişẹ agb'awo lọdọ awọn Oyinbo tọkọtaya ni Opopo Bourdillon, ni Ikoyi.

A gbọ wipe koi ti ju ọsẹ meji lọ ti ọdaran yi de ọdọ Ọgbẹni Haywood ti iyawo Haywood fi sọ wipe on ko ri oruka wura olowo iyebiye on

Nigbati wọn tu iyara Ejes wo, wọn ko ri Oruka şugbọn wọn ri awọn nkan miran ti o ti ji pamọ.

Nigbati ọrọ na de Kotu, adajọ ni ki o lọ san adọta pọnwun tabi ẹwọn oşu mẹrin pẹlu işẹ aşe l'agun.


## Fun Agbara ise l'osan Fun alafia lehin ise ati ere sise



Hommel's Haematogen nfun enia l'agbara gẹgẹbi akọ Malu, tabi bi irin ati awọn nkan miran ti o nmu ara le. Pẹlu agbara Ọkunrin, gbogbo awọn ọmọ rẹ ni yio ni Agbara.

**Fun ilera awon Ebi Re**
MA LO EGBOGI
**HOMMEL'S**
**HÆMATOGEN**

O MBẸ NINU IGO FUN TITA KAKIRI ŞỌBU EGBOGI ILẸ NIGERIA

ati lọdọ Aşoju wa :-

**ALBAN PHARMACY LTD.**

2, Victoria Street, P. O. Box 461,
LAGOS NIGERIA.




## ỌRIKI BAMWo

Bamwo de, alajela ọmọde agbọmọla bi orișa, akọkọluko ogun ti nda'mọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti np'o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o s'ọmọ ti nhohin l'ore. Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri. aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbọ ọrin o kapa inu wọ, o lu jẹdi l'alupa. gbogbo abiyamọ nyọ șẹșẹ. Ela ri i o roju. Ọrẹrẹ ri i o na'gbe bo'ra, Ẹyi npa'lẹmọ lodilẹsọ. ọrẹ ikoko, kosemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de'lu Ibo, o dọga, o de'lẹ Hausa, o d'ọba, gbogbo Onișegun l'o sọ pe ko lẹgbẹ, gbogbo ọmọde lo nfẹ e fun ilera.

*IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4/6d.*
owo ọkọ 1/6d fun igo kan.

THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES

18, Denton Bridge, Street,
P.O. Box 2, Ebute-Mẹta.

## Itan Ku Ku Ku Nipa Awon Alagbara Ile Yoruba

(ob*ẹ*rẹ loju ewe keji)

Awọn arọkin sọ wipe nigbati Ọrunmila nfẹ ngoke lọ si ọrun tabi ti o nfẹ takun lọ si ọrun, Odu Ogbe Șẹtẹ tabi Ogbe lọșẹ ni odu ti o da gbẹhin.

Gbogbo awo ti o mbẹ ni ilẹ Yoruba lo ni aro ti nwọn nda si ara wọn lati kira wọn. Nigbati Babalawo kan ba nfẹ ki ọmọ Awo bi tirẹ, nwọn o wipe:-

"Abọru, Abọye, Abọșẹ," Babalawo ti nwọn ki na a si fesi dahun bayi wipe :- "Aboye Bọșẹ, Ogbo, Atọ ati Airabun.

Njẹ Ọtọtọtọ Ọrọrọrọ, Ọtọtọ la njẹpa, Ọtọtọ la njẹ Imumu, Tori-tori lafi fun Ọba Makin. Ejiogbe.

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eeti-Ofe

## Ofin Ile Wiwo Miran Tun De

Ofin kan tun jade nisisiyi wipe Ilekile ti Alabojuto iṣẹ ile kikọ nilu Eko (Town Engineer) ba ri wipe ile na lewu fun [illegible] enia ti ko si le [illegible], ylo fun Onile [illegible] o ngbe il[illegible] bọ ni [illegible] ki o wo ile na lari[illegible] ọjọ mẹ[illegible]la,

ỌLỌPA MU ADELABU
(O bẹrẹ loju ewe kini)

ilẹ (Land Registry Office) ti ọmọ on ns'iṣẹ. O si gba ponwun mẹwa (£10) na pada bọ.

Ogunṣọla tun sọ wipe awọn enia pọ lọdọ Adelabu ṣugbọn on ṣ'ọgbọn kesi Ali, o ni Ladẹjọ si fun Ali ni owo Pọnwun mẹwa na. Ali mu owo na wọ'le iṣẹ Alaga. Nigbati o ṣe diẹ, Alaga papa jade wa, o si sọ fun on (Ogunṣọla) wipe ki ọmọ on Adigun ma a de ọdọ Ali nigbagbogbo lati mọ bi aye na ba họsi, ọmọ on si para para lọdọ Ali ṣugbọn pabo ni gbogbo rẹ.

Lori eyi ni Ọgbẹni Nicholson fi da Adelabu l'ẹbi wipe o gba owo ibọlẹ lori iwe iwa'ṣẹ James Adigun ati Adeleke Alamu fun aye iṣẹ Aṣọgbo ati Akọda.

Ẹjọ na di rẹrẹ ni Kotu Oniṣeke nilu Ibadan.

Abọ re o!

Jeki o da o loju pe

# KOKO RE YIO DARA

Nigbati o ba ti nlo

# OGUN INU FOUR OAKS SI LARA

Ise ti o nse niwonyi:-

X *Ko ni jeki arun kokoro to mba Koko je ati awon kokoro wewe-we de ara Koko re.*

X *O le ni adorin odun ti opolopo awon Agbe oni Koko ti nlo siwaju awon ogun miran.*

X *Eyi ni pataki ti o to gbekele ti o le re.*

X *Awon eya irin-ise re mbe l'arowoto.*

**Afon ogun ti a npe ni Four Oaks yi mbe ni gbogbo ile Ita'ja, ile-ise Egbe Alasowopo tabi lodo awon Egbe Alasowopo ta oja.**

(Co-operative Produce Marketing Association)

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23316